# ITAN ISẸDALẸ ILU IJẸSHA IJẸBU (Apa Keji)

## Lati Ọwọ Ọmọ Abẹruagba Ijẹsha—Ijẹbu

Olotu, Ẹku ọjọ mẹta ṣe alafia lẹwa .Mo dupẹ lọwọ nyin fun Itan Ilu mi Ijẹsha Ijẹbu ti ẹ ba mi tẹ sita lasiko, ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ, iwaju ni ọpa ẹbiti yio ma resi o Ẹnyin onkawe mi mo sọ fun nyin wipe ti olotu ba le gba mi laye ngo sọ fun nyin bi ilu na ti ṣe dagba to fun nyin ati iru awọn Oloye to njẹ ni ile kọkan.

Ni igba atijọ ile iwe ti o wa ni ilu yi kere pupọ Orukọ ile iwe na si ni St. Judes School. Ẹ ni to ba de ile iwe yi nisisiyi yio mọ wipe ohun rere kan ti NASARET jade wa.

Ti ẹ ba ri ile iwe yi o dabi ẹni wipe ile Ẹkọ giga ni, nitoripe nwọn kọ ile iwe na gẹgẹ bi letter (L) nwọn wa kun ile iwe yi ni awọ yellow.

Ninu gbogbo ile we ti o wa ni agbegbe Ẹkun Ẹmarerun (Ijẹbu Western District Council) yi ile iwe St. Judes School Ijẹsha Ijẹbu jẹ ọkan, nitori awọn ọmọ ti nwọn wa ni ile iwe yi ni nwọn mọwe dada.

Ni ọdun 1957 ọga to wa ni ile iwe yi ni Ọgbẹni J. K. Osinaike ọga yi jẹ ẹni to ni akinkanju ati ṣiṣe, ko fẹ ki Ọmọ ile iwe on ma wa si ile iwe ni ọjọ kan ṣoṣo rara, ti ọmọ kan ko ba waa yan awọn ọmọ ile iwe Ẹgbẹ rẹ lati lọ wo nkan to ṣe ti ko fi wa si ile iwe ni ọjọ na.

To ba je wipe ọmọ na sa'ni ani ki wọn lọ gbe wa ada sẹriya to tọ fun ọmọ na, nitori idi eyi ko si ọmọ ti ki wa si ile iwe.

Ọga ile iwe yi ma npa owe kan wipe aya ọmọde ni wẹre di si ẹgba (stick) ni tuka. Nitori idi eyi ọmọ ti ko ba foju si ẹkọ rẹ pẹlu ẹgba (stick) lo ma fi mọ.

Gbogbo awọn ọmọ ti nwọn lo ṣe idanwo awọn Oniwe marun (Primary Six) ni ọdun 1957 yi je mẹdogun awọn ti nwọn pass jẹ mẹtala awọn meji fail, nje Ọga yi ko ṣe iṣẹ re dada bi.

Ki Oluwa alanu ma ran awọn ọmọ ti nwọn wa ni ile iwe yi lọwọ, ki nwọn le gbe ogo ile iwe wọn ga.

Awọn enia pataki ti wọn kọkọ jade ni ile iwe yi ni Bishop OSIFESO, Alufa I. O. Dada, Alufa J. O. Opelami, Ọmọ Ọba Adebajọ Olowu. Ologbe ( alias ABERUAGBA) ati Ọtua Ọba B. O. Awonubi ati bẹbẹlọ.

Mo bẹ ẹyin enia mi Lọkunrin ati Lobinrin, ki ẹ fi ọmọ nyin si ile iwe, nitori Ẹkọ ṣe pataki nisisiyi

Ilu yi tobi diẹ ati pẹlu awọn enia ti wọn wa ni ilu yi mọ nipa imọtoto, ko si idọti ni arin Ilu yi rara gbogbo wọn ni wọn mọ nipa ibi ti nkan ṣe le ba oju mu.

Ọja to wa ni ilu yi ko ṣe ti ẹnu sọ, nitoripe, irohin Lo to afoju ba. Ọja yi da bi igba ti wọn ba ona Ọja Oyingbo gbogbo nyin lẹ sa mọ bi Ọja Oyingbo ti ma nkun to bẹ gẹ ni Ọja Ilu yi ti tobi to, ero pọ ti wọn ma nna Ọja yi. Ọjọ marun-marun ni wọn manna Ọja yi.

Ile Ọlọrun ti awọn Onigbagbọ ati Awọn Onimọle (Musulumi) kọ si ilu yi dara pupọ to fi jẹ wipe to baje ilu to tobi bi Ijebu-Ode ni wọn kọ ile Ọlọrun yi si ko buru ju, nitori iba diẹ na, nwọn tọju rẹ dada to jẹ wipe ko si koriko kan ni ẹgbẹ ile Ọlọrun yi, gbogbo inu ile ati ode rẹ lo mọ tonitoni. Ki Oluwa na jẹ ki awọn enia wọn yi ma sin On ni Mimọ iwa li ọjọ Aiye wọn gbogbo.

Awọn Oye ti wọn njẹ ni ilu yi ni Balẹ, Oliwo, Ọtun Ọba, Osi Ọba, Apena, Olumale, (Oga awọn Oloro), Alawa, Alase, Ekeku, Alofe, ati Odele ati bẹbẹ.

Ile ti wọn ti njẹ Ọba yi jẹ ile mẹta, Ile Ọmọ-Ọba Belo, Ọmọ Ọba Oyenuga ati ile Adekọya, Ile Adekọya yi lo wa lori oye ni asiko yi, asiko na si owo ati Ọmọ

Ki ẹmi Ọba na o gun, (Amin ) Awọn oye yi ni ti awọn oye Oṣugbo Oliwo, Apena, ati Odele, awọn wọnyi ni ti awọn Oloro. Olumale (Oga awọn Oloro), Alawa ati Aṣipa, Awọn wọnyi ni ti awọn Alagẹmọ, Alofe Ọga awọn Alagẹmọ,

Wo Oju Ewe Kẹfa


**AFRICAN SPECIAL**

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.

# IWE SI OLOTU

## Omu-Aran Nfẹ Omi-Ẹrọ

Ẹ ku ọjọ meta Olotu nba sọpe bi ẹba le gba mi ni aye diẹ nin iwe Irohin Imọlẹ akọmọ lẹgbọn ati oye lati ba Ijọba rere Ipinlẹ Ariwa sọrọ lori ipoti ilu wa wa ati awọn nkan ti anfẹ ninu ilu wa

A nfẹ ẹrọ omi ti a o ma mu, awọn omi ti anmu ko dara to rara osi tun le ko aisan ba enia nitori pe imọtoto jẹ igbakeji iwa bi Ọlọrun gẹgẹbi awọn alakọwe ti ma nwi.

Ki ato ri omi pọn, iṣe kekere kọ ni a nṣe, oni iye igba ti amọ fi ṣe aisan nitori a ti ri omi pọn Nigba miran antin to ibusọ meji si meta ki a to ri omi pọn.

Inu wa yio dun pupọ bi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba le fi Oruko ilu wa si awọn ilu ti nwọn yio fun ni omi ninu ọdun yi.

A ki fi owo-Ori ṣere rara,awa ni akọ nsanwo Ori sinu apo Ijọba a bẹ nyin, ẹ ṣanu wa o, Ẹku ṣẹ o, Olotu

Emi ni
Oladipọ Bandele
OMU—ARAN.

## Ẹ La Eyi Ye mi

Dakun Olotu gba mi laye lati bere ibere mi kekere yi lọdọ awọn onkawe nyin ati gbogbo awọn ọjọgbọn onimọ ijinlẹ ti laakaye wọn jina dẹuu

Ibere na ni yi nigbati mo bi ọmọ mi akọkọ, o jẹ ọmọkunrin ni ọjọ Sunday ni Iya mi bi ọmọ na, osi sọ oruko rẹ ni Sunday

Ṣugbọn nigbati iyawo mi tun bimọ ni ọjọ Sunday ti o kọja yi ọmọkunrin ni o tun bi ni ọjọ Sunday ti mbọ yi ni a si fẹ sọ ọmọ na ni orukọ.

Ẹyin onkawe wa, kini ki nsọ orukọ ọmọ na? Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Emi ni,
Rapheal Abikoye
ALLA

## Ibadan E Ku Ayẹsi

Pẹlu iteriba ni mo fi kọwe yi si Olotu Irohin-Imọlẹ lati bẹbẹ fun aye taape ninu Iwe Irohin rẹ aladun lati ki gbogbo awọn ọmọ ilu Ibadan ati awọn olugbe ilu na fun ariya nlanla ti nwọn ṣe fun Dokita M. I. Okpara olori ẹgbẹ Alakukọ ati Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria nibgati ode ilu Ibadan ni apakan irinajo rẹ pade Ipade awọn enia sa Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria eyiti oṣe ni ibẹrẹ oṣu yi.

Ẹnu kọ irohin ni ayẹyẹ ikini kabọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati ẹgbẹ Alakukọ ṣe fun ni ọjọ na. Nitori lati igba ti oti ku ọjọ melo ti Dokita na yio de ni awọn ọmọ ẹgbẹ ti nkigbe pe ko gbọdọ wa si Ipade na, pẹlu atilẹ-ẹhin awọn Ọba Yoruba melokan bakanna ni nwọn tun ṣe ofin pe ko gbọdọ si ipade ode gbangba Ṣugbọnju gbogbo rẹ lọ oju ti elegan' Okpara gbayi ogba ẹyẹ ni.

Emi ni
Ọmọ-Ọba Laoye
IBADAN

## Okpara, Adegbenro, E ṣeun

Olotu jọwọ gba mi ni aye ninu iwe Irohin-Imọlẹ rẹ oloyin mọmọ ti o kun fun ọgbọn ati oye eyiti koni abawọn lati ki Dokita Okpara ati Alhaji Adegbenro fun iṣẹ ribiribi ti wọn ṣe fun idapọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati ẹgbẹ Alakukọ eyiti Irohin rẹ to wa leti ni ọjọ 'ru ti se Ọjọ keta Osu kẹfa Odun yi ninu ile Odoye



Alhaji D. S. Adegbenro

Ọbafẹmi Awolọwọ nigbati Dokita M.I Okpara se ibewo Ipinlẹ Iwọ-orun Naijiria

Ggobgo enia Naijiria ni o sinu didun si irohin na, nitori ẹgbẹ ti o hun nfẹ ire ati eto Ijọba alafia fun gbogbo enia ile Naijiria ti o ju ẹgbẹ mejeji yi lọ ko si Alero pe nisinsinyi ti ẹgbẹ mejeji ti papọ, ti nwọn si ti ronu jinlẹ nipa aiṣe dede nwọn tẹlẹ nwọn nwu wa jati sa ipa wọn fun eto Ijọba ki ire kari ẹtunbọ ba wa



Dukita M. I. Okpara

ṣe ko dara ki Ijọba Apapọ le bọ si ọwọ ẹyin mejeji o

Suro Baba iwa ẹgbẹ ọlọpẹ tun se bẹ odi ila a

Eku iṣẹ olotu

Emi ni
Ajegboro-Dagba


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* M O D U P E P R E S S
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service,

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.



# EGBOGI JẸDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnse. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni awọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn maa po-owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣubbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun obẹrẹ akana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aike mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ. ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu; pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọn-ṣe tan ni, tabi ti oriṣ y ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kso si panwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ẹkeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gbọro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Pẹlẹpẹlẹ Dọwọ Ẹnyin Awamọto Bọlẹkaja

Lati Ọwọ ALHAJI AWAIYEWAṢERE

Bi a ba npeni ni ole, ko yẹ ki a maa gbe ọmọ ẹran ẹlẹran jo. Ẹru kan si ni o ngmu ni bu igba (200) ẹru. Toto, o e ṣe bi owe o. Diẹ ninu awọn ọmọ onimọto bọlẹkaja ma a nhuwa tani ma a mu ıoı. Nwọn si ma a nhuwa arufin, nigbati nwọn ba ti wa inu mọto akero wọn. Nwọn ko mọ eto, nwọn ko si mọ ẹtọ, nwọn ko si mọ iyi ati ẹyẹ ti nwọn gbọdọ maa fun awọn ero ti nwọn ba gba sinu mọto wọn.

Bi nwọn ba fẹ ṣeṣẹ gba awon ero sinu mọto, nwọn yio ma a tan wọn, nwọn yio si ma a yẹ nwọn si. Ṣugbọn o ṣe ni, ni aanu lati ma a ri i pe, bi awọn ero na ba ti wọ mọto wọn na tan, awọn a wa mọto na ati awọn ọmọṣẹ wọn yio bẹrẹṣi ma a fi abuku olorombo kan awọn ero na. Abuku ko yẹ ọmọ enia. Abuku ko tọ si mi. Abuku tọ si ẹ.

Nwọn yio si gba ero koja ala Nwọn yio ko wọn jọ sinu mọto bi sıadinni elege. Nwọn yio si maa jagbe mọ wọn pe, ẹ sun sibi, ẹ sọun, Bi nwọn ba si ti ba ero ṣe adeun lati gba sile kan lati ibusọ kan si ibusọ kẹta tabi kẹrin nwọn yio si sọ owo wọn' di sile kan ati tọrọ, nwọn yio si tak·ı mọ wọn lọwọ bi ọmọ alanda,

Nwọn a si ma a nwa mọto wọn ni iwakuwa Gbogbo irufẹ iwa bayi ko dara rara, ko sunwọn. Ki iṣe iwa Ọmọluwabi Mo bẹ ẹnyin awamọto, ẹ ṣe suru, ẹ ronujinlẹ, ẹ jirẹdọ, ẹ lọ jawọ kuro ninu eepo epa ti ko ni Ọmọ ninu Iwa ire ni o yẹ Ọmọ enia.

Iwa ire ni o pe iwa buburu ko tọ si ẹ, ko si tọ si mi Mo bẹ ẹnyin Onimọto ẹlẹrẹkẹ eebu, abuni bi ẹni nla oyin, ẹ ye ṣe ẹrẹkẹ eebu mọ Ẹṣan m bẹ.

Ati oore ati ika, ọkan ki i gbe. Ẹni ba ṣe ire yio ri ire, ẹni ba si ṣẹ ibi, yio ri ibi.

Bi ẹ ba si ṣe akiyesi dada, ẹ o ri i pe, ẹnu buburu ma a ıta ı mọ enia ni o si ni iwa Lẹrimaoi ,t! iwa janduku, ati iwa ọmọjẹka ma a otanılọṣi ni pẹlẹ pẹlẹ dọwọ ẹnyin onimọto na o.

Mo bẹ ẹnyin Ọlọpa gidigidi, ẹ jọwọ, ẹ ba wa tubọ mojuto, ẹ ba wa tubọ ṣe ikilọ fun awọn onimọto a ni awọn awamọto Bọlẹkaja, ki nwọn ye ṣe ẹmi ọmọ enia ni iṣekuṣe.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Ṣọra ki o ma ṣe aṣiṣe, maṣe ba ẹnikan ja rara, nitori ọrọ ijiyan ti ko ni lari le mu ija wa.

PISCES (Feb 21 - March 20) Aifarabalẹ rẹ nfẹ atuuse lọ kọ ifarabalẹ o si ye ki o ma ronu jinlẹ, nitoripe ẹnikan nfẹ ọ, o nronu nipa tirẹ, o nfẹ ki on pẹlu rẹ jijọ pada sọrọ rere kan.

ARIES (March 21 - April 20) Iwa rẹ yio mu ẹnikan binu si ọ, tobẹ ti iwọ ko tilẹ ni fẹ mọ pe ẹnikan mbinu si ọ, ire ojiji kan yio yọ si ọ lairo tẹlẹ.

TAURUS (April 21 - May 20) Maṣe ba wọn kẹgbe wipe ẹ ko ṣiṣẹ mọ. Bi o ba ti ṣe iṣẹ si, bẹni i.e yio fi tẹle ọ lẹhin. ki o si gbọ afẹ ati faari. Iwọ yio gba owo atẹhinwa kan.

GEMINI (May 21 - June 21) Edekoyede kan yio fa ibinu awọn ọrẹ rẹ si ọ nse ni ki o ba wọn pari ija na, yọnu si wọn ki ẹ si ma ki ara nyin, ninu eyi ni iwọ yio ri owo pupọ.

CANCER (June 22 - July 23) Maṣe jiyan kan ti ko mọyan lori loni gbogbo nkan ti iwọ yio ba se ni ọjọrọ oni, ṣe e pẹlu iṣọra ki jamba ma ba ṣẹlẹ si ọ, maṣe jẹki awọn enia mu ọ lati sọ ohun ti o ko fẹ.

LEO (July 24 - Aug 22) Gbogbo ilọsiwaju rẹ ati ipada sẹhin rẹ ofo ni gbogbo rẹ ẹniti o mba se alatako ko nse ẹniti o buru to bẹ, maṣe jẹki ẹnikan ti o lagbara ju ọ lo binu si ọrọ rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Gbọn bi ejo, ki o si ni iwa tutu bi adaba. O daju pe oju ko ni ti ọ Ọgbọn ori rẹ ni ki o tẹle ire mbọ wa nibe.

LIBRA (Sept. 24-Oct 23) Ẹni lati sọ asọpari ọrọ owo kan ti o mbẹ nilẹ ọgbọn ori rẹ yio kọ ọ ni ohun ti iwọ yio ṣe. Ṣugbọn ṣọra nitori owu jijẹ ati oju buruku awọn ti yio ma wo ọ.

SCOPIO (Oct. 24-Nov. 22) Bi o ba ni lati rin irin ajo, maṣe jafara, tete bọ soju ọna, ire mbẹ fun ọ ninu biba alejo sọrọ tabi ajeji enia

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec. 21) Ohun ti nṣe ọ nisisiyi le pupọ, maṣe tẹle ohun ti iwọ nro rare wọ inu ẹgbẹ awọn ti o nwa ire ati alafia rẹ maṣe fi ẹmi rẹ wu ewu.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Bi iṣẹ rẹ ba duro nipa wahala ati ogbọn rẹ opin ko ni pẹ de si gbogbo rẹ, nitorina jẹki ọrọ iwọ pẹlu awọn to nba ọ gbe yẹ ara yin wo.


## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awon Faranse gidi ti a npe ni

**'CORSIVER'S**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹra u tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba ı lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisun ba nyọ ọ lẹnu ikẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn anodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na ojẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria. (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ egbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrinla oṣu yi (14/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titu ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ ki ẹsi tete d

LATEEF BAB LOLA
Akọwe Agba

# Ẹgbẹ A. G. Ati N.C.N.C. Ni Yio Papọ Fun Idibo Si Igbimọ Ijọba Apapọ

OSHOGBO:— Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ni yio jijọ papọ fun idibo si Ile Igbimọ Aṣofin ti Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria ti nwọn yio ṣe ninu ọdun yi. Eleyi jade lati ẹnu Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakukọ ninu ọrọ to sọ larin irin ajo rẹ si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nigbati Olotu na ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ nsọrọ ni Ile Oloye Kọlawọle Balogun ni Oshogbo ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi.

Dokita Okpara si tun sọ si i pe ẹgbẹ on ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio ma a wa pọ lati fun gbogbo idibo ni orile ilẹ Naijiria lati le fi Ijọba ti yio mu ọkan awọn enia ile Naijiria ni irọrun,



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Olotu ipinle ila orun si tun sọ wipe iṣọkan si ti wa fun ẹgbẹ on ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe iwa awọn ẹgbẹ mejeji ti ko ti ye ara wọn lati igba yi si ti dopin ati papa julọ ko si iya soto larin ẹgbẹ na bayi.

Dokita Okpara si tun sọ pe o yẹ fun awọn ẹgbẹ meji na bayi lati papọ ati lati mu eto ijọba rere lelẹ fun awọn enia ile Naijiria.

Olotu na si tun sọ pe ẹgbẹ on Ọmọ si ti wa lati gbogun ti awọn enia to ba fẹ gbogun ti ominira awọn enia Naijiria.

Olotu ipinle ila Orun si tun sọ pe lati oni yi lọ ni ẹgbẹ on yio ti doju ija kọ awọn enia ti ko ba fẹ tẹle eto ofin.

Dokita Okpara si tun rọ awọn ọdọ ile Naijiria lati fi tifẹtifẹ ni isowọpọ pelu ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre lati le gbogun ti awọn oṣelu ti ko fẹ ilọsiwaju awọn enia ilẹ Naijiria

Dokita Okpara si tun ṣe eto ipade na ni ọgba kan ni Ilesha. Olotu na si tun sọ fun awọn enia ilu Ijesha pe ẹgbẹ on ati ẹgbe Afẹnifẹre si ti papọ nitori ede awọn ẹgbẹ na si jẹ ọkan nipa eto ilọsiwaju ati idagbasoke ilẹ Naijiria. Dokita Okpara si tun rọ awọn enia Ilesha lati ni isowọpọ pelu egbe N C N C

Nigbati Dokita Okpara si sọ eyi, gbogbo awọn enia si ho iho ayọ pelu Olotu na ati pe osi tun sọ pe awọn yio fi opin si ẹgbẹ oṣelu ti ko fẹ ilọsiwaju awọn enia.



Dokita M. I. Okpara

Dokita Okpara si tun sọ pe egbẹ on N C N C ko ni fi aye silẹ ẹni kankan lati jẹki nwọn gba ominira wọn mọ wọn lara.

Nigbati olotu na pari ọrọ rẹ ni awọn enia si bẹrẹ si kegbe nipa eto enia kika, olotu na si tun da wọn lohun pe bayi pe ki nwọn ṣe suru pe ile ẹjọ wa ni yio ṣe idajọ lori rẹ. O si tun sọ pe ko si ẹnikankan to mọ iye enia ilẹ Naijiria.


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN'

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn maa powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri ingwa ninu awọn ogun o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu kù ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣubbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun oberẹ akana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba se igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

ATI NI AWỌN ŞOBU IBADAN:—
IṢẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

## Modupẹ Printing Press

16, Bamgbose Street,
Phone 21985, Lagos.

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 717 FRIDAY, JUNE 12, 1964 (2D)


## Adamọdi Ọlọpa Kan Wẹwọn Oṣu Meta

KAFANCHAN:- Malam Dambo, adajọ kotu Ijọba Ibile Kafanchan, ṣe idajọ pe ki ọdaran adamọdi ọlọpa kan, Emmanuel Ganiyu, ẹni ọdun mẹrindinlọgbọn lọ si ẹwọn oṣu mẹta nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan an ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti ise ọjọ kọkanla oṣu yi.

Ṣiwaju eyi ni ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣejọ ti ṣe alaye pe, ọdaran na wọ ọkọ reluwe, ko sanwo, nigbati awọn alaṣẹ ọkọ bere owo lọwọ rẹ, o sọ fun wọn pe Ọlọpa ni on.

Nigbati nwọn wo inu ẹru rẹ, nwọn ri fẹre ọlọpa, bata ati iwe pokiti ọlọpa kan ṣugbọn oruko ẹlomiran lowa ninu iwe na ki iṣe ti ọdaran na.

Ọdaran na ṣe alaye pe, iṣẹ ọlọpa wu on pupọ, lati igbati ẹgbọn on ti nṣe iṣẹ na, nigbati osi kuro lẹnu iṣẹ na ni on ba ko bata, fere ati iwe rẹ ti on si fi nhalẹ mọ awọn enia kakiri ilu.

Ṣugbọn adajọ na sọ fun pe, ki o lọ fi ẹwọn oṣu mẹta jura, ti o ba si de lati ọgba ẹwọn, ti iṣẹ ọlopa ba wu u ki o lọ ṣe iṣẹ Ọlọpa lẹhin ti o ba jade lẹwọn.

## Awọn Asiwaju Ijọ Ọlọrun Sọ Pe:

# Ẹ FUN AWỌN OṢIṢẸ NI ẸKUNWO ỌWO — OSU

EKO:- Gbogbo ile lo kun sọsọ ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ awọn asiwaju ijọ Ọlọrun ti nwọn ṣe ipade pajawiri ni oru ana lori eto idaṣẹ silẹ eyiti gbogbo awọn oṣiṣẹ ati oluko fi da iṣẹ silẹ lati ọjọ kini oṣu yi lori ọrọ ẹkunwo owo oṣu ati owo ọọya eyiti Igbimọ oluwadi Morgan pa laṣẹ fun Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria lati san fun awon oṣiṣẹ.

Awọn aṣiwaju ijọ Ọlọrun na sọ pe, fun ire, anfani ati ilọsiwaju orilẹ ede wa o yẹ ki ijọba apapọ san owo na fun awọn oṣiṣẹ awọn si fi ara mọ igbimọ Morgan lori iwadi rẹ.

Igbimọ na ke si Apapọ ilẹ Naijiria pe lẹhinti awọn ti fi ikun luku ti awọn si ti jiroro lori ọrọ kosi imọran kan ninu eyi ti igbimọ Oluwadi Morgan ṣe ti ijọba le fi ọwọ rọ sẹhin.

Ninu ipade na. Ẹni-ọwọ Alufa Seith Kalẹ ti iṣe Bishọbu agba fun ilu Eko ẹni to ti fi igba kan jẹ alaga igbimọ fun awọn oluko jakejado Naijiria lo ṣe alaga ipade yi.

Agbọrọsọ awọn aṣiwaju na fi ye oniwe irohin wa gẹrẹ ti nwọn pari ipade na pe: "Awa gẹgẹbi aṣiwaju ijọ Ọlọrun ti nkọ ominu pẹlu ifoya lori ohun to le gbẹhin idaṣẹ silẹ awọn oṣiṣẹ nwọn yi"

Ati nfẹ lati ri alakoso Apapọ Ijọba Naijiria tabi lati ṣe eto lati ba apapọ alaṣẹ ijọba na jiroro "lori rudurudu to wa ni ilu yi ṣugbọn gẹgẹbi iṣẹ wa a ko iti le mu ero ọkan wa sẹ ti ti bi a ti nse ipade yi"

Ọrọ yi ti wa nhan si gbogbo araiye nisisiyi, awa paapa na si fi ara mọ lẹhin ọpọlọpọ ijiroro pe, o tọ, o si yẹ ki Ijọba san owo na fun awọn oṣiṣẹ.

"Ṣugbọn boya bi a ba ri Ijọba kan ti o lọ tabi ti ko fẹ lati gba imọran eyiti Igbimọ Morgan ṣe pe, o kọja agbara on, A gba ẹnyin Ijọba bẹni imọran pe ki o tete yara wa ọna ti Ijọba na yio gba san ẹkunwo fun awọn oṣiṣẹ, nitoripe ika to ba to si inu lafi irẹmu"

Ṣugbọn ao le Akata jinna ka to ba adiẹ wi nitori idi eyi o wa kesi gbogbo awọn oṣiṣẹ patapata pe ki nwọn mu suuru lori ọrọ to de lẹ yi nitoripe ohun ti a ba fẹle mu ki i bajẹ.

"Gbogbo awa asiwaju ijọ ni Eko ati agbegbe rẹ kesi Apapọ Ijọba peki nwọn san ẹkunwo owo oṣu na fun awọn oṣiṣẹ a si wa kesi Alhaji Abubakar Tafawa Balewa fun akọtun ipinnu lori ọrọ na eyiti yio jẹ anfani fun gbogbo enia ni orilẹ ede yi ati ti Ijọba ilẹ wa."

Lati Oju Ewe Kini

Obinrin na sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, awọn ti dakẹ ri ni, ti awọn si nwo ohun ti Ijọba fẹ ṣe lori ọrọ ẹkunwo oṣu awọn oṣiṣẹ yi ṣugbọn nisisiyi ti awọn ti awọn nreti ohunti Ijọba fẹ ṣe ti ko ṣi ye awọn, awọn ti pinnu lati ma lọ ta ọja ni ọja mọ.

Obinrin na sọ pe, awọn fun Ijọba ni ọjọ meji pere ati sọ ero wọn jade ki nwọn si san owo na fun awọn osiṣẹ

Bi Ijọba ko ba san owo na fun wọn ti awọn oṣiṣẹ ko si pada si ẹnu iṣẹ wọn ni ọla, gbogbo obinrin Eko ni yio to lọ si Ile Igbimọ Apapọ Ijọba lati lọ fi ipinnu awọn han Ijọba

Obinrin na wa be gbogbo awọn ọkunrin ti nwọn koba ni ba onjẹ nilẹ nigbati nwọn ba de lati ibi iṣẹ wọn ni ọla pe, pe ki nwọn maṣe bi nu. O ni awọn ti nwo awọn Ijọba niran lati ọjọ yi wa ṣugbọn awọn ko tun le dakẹ maa wo Ijọba lọ mọ bi ọrọ na ti ṣe nlọ yi.

Awọn obinrin Ọlọja Eko ti fun Apapọ Ijọba ni ọjọ meji oni ati ọla lati fun oṣiṣẹ ni Ẹkunwo-owo oṣu ti nwọn nbere fun, bi bẹẹ kọ awọn obinrin yio da iṣẹ silẹ Siwaju eyi ni, ni Ọgbẹni Michael Imodu ṣe alaye pe gbogbo awọn oṣisẹ ko gbọdọ pada si ẹnu iṣẹ wọn titi Ijọba fi san ẹkun owo osu ati owo ọọya Osu mẹfa na fun wọn,

Ọgbẹni Imondu sọ pe ,'Iro ni Redio npa ti o nsọ wipe awọn Osisẹ ti pada si ẹnu iṣẹ "Ọgbẹni Imodu wa berepe "Bi awọn ba pada si ẹnu isẹ wọn kinise ti Ijọba fi tun paṣẹ pe ki awọn Ọlọpa ma a lọ duro si ile isẹ kiri?

Owa rọ gbobgo awọn osisẹ pe,Ẹnikẹni ko gbọdọ lọ si ibi isẹ awọn ti wọn bi si lọ "ti awọn ba gbọ ki wọn fi iya ti o tọ jẹ iru wọn ọdalẹ akusẹ awọn ni osiṣẹ na

Awọn osisẹ na yio tun se ipade ni Apapọ Oloye ni agogo mejila ọsan oni

## Itan Ijẹbu—Ijẹsha

Lati Oju Ewe Keji

Alaṣẹ ati Ojuwa Orisa awọn wọn yi ni ti awọn Alagbo Ẹlẹku ati Alawa. Awọn Oye miran wa to jẹ wipe nkole fi ẹnu kan loni yi rara Ti ngo fi silẹ di ọjọ miran

Ni ilu yi ọga awọn Alagẹmọ kan ti wa to jẹ wipe ti Ọdun Agẹmọ ba ku Osu kan ko ni fi ẹsẹ kan ilẹ rara titi ti wọn ma fi lọ se Ọdun Agẹmọ ni Imosan.

Orukọ ọga awọn Alagẹmọ yi ni Odidi Sabẹjẹjẹ, ko si Obirin to gbọdọ pade rẹ ti wọn ba fẹ lọ se Ọdun Agẹmọ nitori idi eyi ni wọn ma fi lo ọna ba yi pe;-ọna o torisa iku aiye eke, Obirin kiwo, owo fere oku fere. Awọn Agba ama pa lowe wipe Ọmọde ki ifi Agẹmọ sita wo Orisa miran Agẹmọ jẹ orisa to jẹ wipe o dara

Se ẹnyin na mọ wipe ti Egungun wa ba jo dada ori aya ọlọkọ rẹ awọn Ọmọde Ilu yi jẹ Ọmọ ti nwọn ni aisiki ti wọn ṣi tun mọ bi ilaju tiri ni aiye isiyi Mo ki yin lọmade ,lagba wipe Oluwa jẹ ki ẹ legbe Ilu yi soke ju eyi ti awọn Babala nyin ati Ẹgbọn nyin ti se yi lọ,

Modupẹ lọwọ Olotu iwe Irohin Imọlẹ nyin cloyin momọ yi, ki Oluwa Alanu ma ba nyin gbe lai ati lailai ipade wa bi oyin.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbgose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street, Lagos (11/6/64)